# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸLẸ̀

## APẸẸRẸ TI Ọ̀RUN

## Ìtàn ...

**EKSODU 24:1-25**

Oluwa kò iti fi àmì nlá alagbara ati iyanu hàn rí gẹ́gẹ́ bi ìgbà ti O gba awọn ọmọ Israeli kúrò ninu oko ẹrú li Egipti. Iyọnu lori iyọnu li o njanu Ijọba Farao titi ti a fi fi agbara mu u lati tú awọn ounde rẹ sílẹ̀. Lẹhin náà, ni Oluwa pín okun pupa nínyà, O sì fún awọn orilẹ̀-èdè kekeke ní ominira, ti awọn ọ̀tá wọn si ṣègbé sinu òkun lẹhin wọn.

Lẹhin ti wọn dé aginjù, Ọlọrun ya ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ ènìyàn Rẹ̀ lẹnu nígbà ti o darí wọn lọ sí ìhà guusu - eyiti iṣe idojukọ Ilẹ̀-Ileri. Oluwa mọ̀ pé ki wọn to mura lati gba iní wọn, wọn gbọ́dọ̀ ti múra tán, ki wọn ki o si kọ́ bi a ti ngba Ọlọrun gbọ́. Bi wọn ti nrìnrìn àjò lọ si òkè Sinai, Ọlọrun npèsè gbogbo àìnì wọn fun wọn. Nigbàti ebi npa wọn, Ọlọrun fi manna lati ọrun bọ́ wọn. Nígbàtí ọ̀fun ngbẹ wọn, Oluwa mu omi jade lati inu àpáta. Nígbà ti ọ̀tá déédé yọjú si wọn lojiji latẹhin, wọn ṣegun ni ọ̀nà iyanu.



Ni iparí, awọn ọmọ Israeli péjọ ni ìsàlẹ̀ òkè mímọ́ náà. Níbẹ̀, Ọlọrun ṣe ohun kan ti kò iti ṣe ri tẹ́lẹ̀. Ọlọrun sọ̀rọ̀ - li etí gbogbo orilẹ̀-èdè - majẹmu Rẹ̀, Ọ̀fin Mẹwa. Lẹhin ti Oluwa ti sọ òfin Rẹ̀ li ohùn òkè, O pe Mose lọ sí orí òkè Sinai lati gba ojulowo òfin ti a kọ si ara okuta. Ṣùgbọ́n Ọlọrun tun fun ni nkan miran. Bi mose ti ṣe wa ni ori òkè sibẹ̀ pẹlu Oluwa ni ogoji ọ̀sán ati ogoji òru, Mose gba ìlànà li ẹ̀kún rẹ́rẹ́ lati kọ́ tẹmpili mímọ́ tó dára tí ó sì kéré fun Ọlọrun. Yio jẹ́ apẹrẹ kekeré ibùgbé Rẹ̀ ni ọrun. Àwòrán iyebiye yi yio jẹ ẹ̀kọ́ ti o ni igun mẹta fún gbogbo ayé lati mọ ìpinnu Ọlọrun lati gbà wá kúrò lọ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀

AMAZING FACTS

## Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọ̀ọkan tán.

1. Kinni ohun ti Ọlọrun sọ fun Mose pé ki o kọ́, ati pé kinni ìdí rẹ ?
   **Eksodu 25:8**
   Ki nwọn ki o si ṣe _________ kan fun mi; ki emi ki o le _________ aarin wọn.

2. Kinni Ọlọrun fẹ́ ki awọn enìyàn Rẹ̀ má a kọ́ ninu àgọ́ náà ati ninú ijọsìn nibẹ̀?
   **Orin Dafidi 77:13**
   Ọlọrun, _________ rẹ mbẹ ninu ìwà-mímọ́: tali alagbara ti o tobi bi Ọlọrun?
   Àkíyèsí: Ọ̀nà Ọlọrun tàbí ipinnu ìgbàlà Rẹ̀ ni a fi hàn ninu ibi mímọ́ li ayé. Ohun gbogbo ti ó wà ni ibi mímọ́ tàbí ti o sopọ̀ mọ ijọsin rẹ jẹ àmì nkan ti Jesu yio ṣe lati gbà wá. Òye ìgbàlà ko ti le ye wa pátápátá bikòsepe a kọ̀kọ̀ ni òye nipa ibi-mímọ́ ati ijọsìn rẹ. Ó jẹ́ ẹ̀kọ́ tó lagbára, t'ó sì jẹ́ ẹ̀kọ́ onigun mẹta to nsalayé igbéṣẹ̀ ìgbàlà.

3. Nibo ni Mose ti ri apẹrẹ tàbí àwòrán àgọ́ náà?
   **Eksodu 25:40**
   Si kiyesi i, ki iwọ ki o ṣe wọn gẹ́gẹ́ bi _________ wọn, ti a fihàn ọ lori _________.
   Àkíyèsí: Àwòrán ati bi ibi mímọ́ náà yio ti ri gan ni kíkọ́ rẹ, ni a ti fi han Mose nipaṣẹ Ọlọrun ni orí òkè Sinai (Heberu 8:5). Eleyi jẹ́ apẹrẹ kékeré fun ojúlówó ibi mímọ́ ti ọrun.




Ibi mímọ́ àkọ́kọ́ tabí àgọ́ jẹ́ eyi ti o wuni lọ́pọ̀, àwòráb rẹ̀ jẹ́ ìwọ̀n (ẹsẹ̀ marundinlogun (ẹ́ú) sí ẹsẹ̀ marundinlaadọta (èú)). Níbẹ̀ ni ìfarahàn Ọlọrun wà èyítí o kọja ọgbọ́n ènìyàn, bẹ́ẹ̀ni a si ṣe ijọsin àrà ọ̀tọ̀ nibẹ̀. Ogiri rẹ̀ ni a fi igi akasia ti o dúró sánsán ṣe, a si fi wúrà bò ó (Eksodu 26:15-19, 29). Ìbori rẹ ni a bò ní ìpèlé mẹrin - aṣọ ọ̀gbọ olókun wiwẹ, aṣọ-títa onirun ewurẹ, awọ àgbò ti a sè ni pupa, ibori awọ seali lori rẹ̀ ( ẹsẹ 1,7,14). O ni ìyàrá meji: ibi mímọ́ (ẹsẹ̀ marunḍ dilogun (15) si ẹsẹ̀ ọgbọ̀n (30)), ati ibi mímọ́ julọ (ẹsẹ̀ marundilogun (15) si ẹsẹ̀ marundilogun (15)). Má a tọka si àwòrán òkè yi bi o ti nyẹ ẹ̀kọ́ náà wò.

4. Irú ohun ọ̀ṣọ́ wo ni o wà ni àgbàlá ?
   **A. Eksodu 29:18**
   Iwọ o si sun gbogbo àgbò naa lori _________ naa: ẹbọ _________ ni si OLUWA: oorùn dídùn ni, ẹbọ ti a fi iná ṣe si OLUWA.
   **B. Eksodu 30:18**
   Iwọ o si ṣe _________ idẹ kan, ati ẹsẹ̀ rẹ̀ idẹ, fun wíwẹ̀: iwọ o si gbé e ka agbedemeji àgọ́ ajọ, ati pẹpẹ nì, iwọ o si pọn omi sinu rẹ̀.
   Àkíyèsí: Pẹpẹ ẹbọ sisun náà (Eksodu 27:1-8) ni ibi ti a ti nfi awọn ẹran ṣe irubọ. Ó wà ni àgbàlá, ni kété ti a ba ti jade si ìta, nibi atiwọ inu àgọ́ náà. Pẹpẹ yi dúró fún agbelebu Kristi. Ẹran ìrúbọ dúró fun Jesu, ẹbọ to gajù (Johannu 1:29). Agbada náà (Eksodu 30:17-21, 38:8) jẹ́ rọba ìwẹwọ́ nla ti a gbé sí ẹnu ọ̀nà a ti wọ inú ibi mímọ́ náà pẹlu pẹpẹ ẹbọ sisun. Nibẹ̀ ni awọn alufa ti ma nwẹ ọwọ́ ati ẹsẹ̀ wọn ki wọn to wọ inu àgọ́ lọ tabi ki wọn to rú ẹbọ. Omi náà dúró fun baptismu, ìwẹ̀nùmọ́ kúrò ninu ẹ̀ṣẹ̀ ati ìbí titun.

5. Kinni ohun èlò gbẹ́nàgbẹ́nà mẹta ti ó wà ni ibi mímọ́ náà?
   **A. Numeri 4:7**
   Ati lori _________ _________ nì, ki nwọn ki o nà aṣọ aláró kan si, ki nwọn ki o si fi awopọkọ sori rẹ̀, ati ṣibi ati àwokòtò, ati igo ohun didá: ati àkàrà ìgbà gbogbo ni ki o wà lori rẹ̀.
   **B. Numeri 8:2**
   Sọ fun Aaroni, ki o si wi fun n pé, Nigbati iwọ ba tàn fitila, ki fitila mejeje naa ki o ma tàn imọlẹ lori _________.
   **D. Eksodu 30:1**
   Iwọ o si ṣe _________ kan lati ma jó _________ lori rẹ̀: igi sittimu ni ki iwọ ki o fi ṣe e.
   Àkíyèsí: Tabili àkàrà ìfihàn (Eksodu 25:23-30) dúró fun Jesu, ounjẹ iyè (Johannu 6:51). Ẹka ọ̀pá fitila meje naa (Eksodu 25:31-40) dúró fun Jesu, ìmọ́lẹ̀ ayé (Johannu 9:5; 1:9). Fitila òróró nṣe apẹrẹ Ẹ̀mí Mímọ́ (Sekariah 4:1-6, Ifihan 4:5). Pẹpẹ tùràrí (Eksodu 30:1-8) dúró fún àdúrà awọn ènìyàn Ọlọrun (Heberu 5:7).

6. Kinni ohun pàtàkì ti ó wà ni ibi mímọ́ ?
   **Eksodu 26:34**
   Iwọ o si fi ìtẹ́-àánú sori _________ ẹ̀rí nì, ni ibi mímọ́ jùlọ.
   Àkíyèsí: Ohun kan soso tó wà ní ibi mímọ́ jùlọ (Eksodu 25:10-22) ni apoti ẹ̀rí, ti a fi igi akasia ṣe pẹlu wúrà fun ibori rẹ. Ni ori rẹ ni awọn angẹli meji ti a fi wúrà líle mọ wà. Ìbòrí apoti náà ni a npè ni ìtẹ́-àánú (Eksodu 25:17-22), níbẹ̀ ni ifarahàn Ọlọrun ngbé. Ipò yi nṣe àpẹrẹ ìtẹ́ Ọlọrun ni ọrun, èyítí o jẹ wípé o wà ni aarin awọn angẹli meji pẹlu (Orin Dafidi 80:1; Isaiah 6:1,2).

7. Kilo wà ninu apoti náà?
   **Eksodu 25:21**
   Iwọ o si fi ìtẹ́-àánú naa sori apoti naa; ati ninu apoti naa ni iwọ o fi _________ ti emi o fi fun ọ sí.
   **Deuteronomi 10:4,5**
   Oun si kọ òfin _________ sára walaa wọnni, gẹ́gẹ́ bi o ti kọ ti iṣaaju, ti OLUWA sọ fun nyin lori òkè naa lati inu aarin iná wá li ọjọ́ nì; OLUWA si fi wọn fun mi, Mo si padà, mo si sọkalẹ̀ lati ori òkè naa wá, mo si fi _________ wọnni sinu apoti ti mo ti ṣe; nwọn si wà nibẹ̀, bi OLUWA ti pàṣẹ fun mi.
   Àkíyèsí: Ọlọrun kọ majẹmu Rẹ̀ pẹlu ika oun tikara Rẹ̀ si orí tabili okuta meji, a si gbe wọn sinu apoti naa. Ìtẹ́-àánú sì wà lókè wọn, eyi to tumọ̀ si wipé bi awọn eniyàn Ọlọrun ba sa ti jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wọn ti nwọn si kọ ọ sílẹ̀ (Owe 28:13), wọn yoo rí àánú gbà nípàsẹ̀ ẹ̀jẹ̀ tí a

wọ́n sí ara ìtẹ́ àànú lati ọwọ́ alufa (Lefitiku 16:15,16). Ẹ̀jẹ̀ naa dúró fun ẹ̀jẹ̀ ti Jesu ta sílẹ̀ lati mu ìdàrìjì ati iwẹnumọ́ wá fún gbogbo ènìyàn (Matteu 26:28; Heberu 9:22).

8. Kinni ìdí ti a fi nílò ẹran fun irubọ ninu Majẹmu Lailai nibi ìjọsin àgọ́?
   **Heberu 9:22**
   O si fẹrẹ jẹ́ ohun gbogbo li a fi ẹ̀jẹ̀ wẹ̀nù gẹgẹ bi òfin; ati laisi _________ kò si idariji.
   **Matteu 26:28**
   Nitori eyi li ẹ̀jẹ̀ mi ti majẹmu titun, ti a ta silẹ fun ọ̀pọ̀ eniyàn fun _________ _________.

   Àkíyèsí: Fifi ẹ̀jẹ̀ ẹran rubo jẹ́ ohun to ṣe pàtàki lati ran awọn ènìyọ́ àn lọ́wọ́ lati mu ki wọn ni òye pé laiṣe wípé Jesu ta ẹ̀jẹ̀ silẹ lori agbelebu, kò ni isi ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀ rárá. Òtítọ́ ti o bani lẹ́rù ni pé, ikú ni èrè ẹ̀ṣẹ̀. Nigbati gbogbo ènìyàn ti ṣẹ̀, gbogbo wa lo yẹ ki a kú - gbogbo wa ni iba sì ti kú, bikoṣe pe Jesu fi ayé pípé Rẹ̀ silẹ̀ lati kú ni ipò wa lati san gbèsè ẹ̀ṣẹ̀ wa. Ẹlẹ́ṣẹ̀ mu ẹran irubọ rẹ̀ wá, ó sì fi ọwọ́ ara rẹ̀ pa á (Lefitiku 1:4,5). O jẹ́ ẹ̀sù ipaniyàn ti o si bani lẹ̀rù jọjọ, àti ìwúrí fún awọn enìyàn pẹ̀lú otitọ pé ẹ̀ṣẹ̀ lo mu ki Jesu kú. Nítorí ìdí èyí, wọn nwo igi agbelebu fun ìgbàlà, nigbati a nwo ẹ̀hìn fún agbelebu fún ìgbàlà. Ko tun si orisun ìgbàlà miran mọ́.

9. Nigbati a ba fi ẹran ṣe irubọ fún ẹ̀ṣẹ̀, kilo ma nṣẹlẹ̀ si ẹ̀ṣẹ̀ náà?
   **Lefitiku 1:4-5**
   Ki o si fi _________ rẹ̀ le ori ẹbọ sisun naa; yio si di itẹ́wọ́gbà fun un lati _________ fun un, Ki o si pa akọmalu naa niwaju OLUWA: awọn alufa, awọn ọmọ Aaroni, yio si mú ẹ̀jẹ̀ naa wá, nwọn o si fi ẹ̀jẹ̀ naa wọ́n ori pẹpẹ nì yíká ti mbẹ li ẹnu-ọ̀nà agọ́ ajọ.

   Àkíyèsí: Nigbati ẹlẹ́ṣẹ̀ ba fi ọwọ́ le orí ẹran naa, ti o si jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀, ẹ̀ṣẹ̀ naa yio kúrò lati ara ẹlẹ́ṣẹ̀ bọ́ si ara ẹran náà. Nitori naa, li ẹran naa fi jẹbi ti o si gbọdọ̀ san ìjìyà ikú. Èyi dúró fun Jesu ti o ru gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ wa lọ.

10. Nigbati a ba fi ẹran irubọ ṣe irubọ fun gbogbo ijọ, kilo ma nṣẹlẹ̀ sí ẹ̀ṣẹ̀ náà?
    **Lefitiku 4:17**
    Ki alufa naa ki o si tẹ̀ ìká rẹ̀ bọ̀ inu ẹ̀jẹ̀ naa, ki o si _________ ọn nigba meje niwaju OLUWA, níwájú aṣọ-ikele.

    Àkíyèsí: Alufa yio wọ́n nínú ẹ̀jẹ̀ náà níwájú aṣọ-ikele ninu àgọ́ ni ibi mímọ́, eyi ti o nsapẹrẹ pe ẹ̀ṣẹ̀ yóò kúrò lára àwọn ènìyàn bọ́ sí ara àgọ́. Nígbàtí Jesu gòkè re ọrun lẹhin ikú Rẹ̀, o fi ẹ̀jẹ̀ Rẹ̀ sílẹ̀ (gẹ́gẹ́ bi awọn olori-alufa ìgbani ti ma nṣe) lati fihàn pé, a ti dari gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ wa jì wá bí a ba ti jẹ́wọ́ ní orúkọ Jesu (1 Johannu 1:9).

11. Kinni àmì àgọ́ mejì ti Jesu mu ṣẹ fún wa?
    **1 Korinti 5:7**
    Nitori náà ẹ mu iwukara atijọ kuro ninu nyin, ki ẹnyin ki o le jẹ́ iyẹfun titun, gẹ́gẹ́ bi ẹnyin ti jẹ́ aiwukara. Nitori a ti fi _________ wa, ani Kristi, rubọ fu wa.
    **Heberu 4:14**
    Njẹ bi a ti ni _________ _________ nka kan, ti o ti la awọn ọ̀run kọja lọ, Jesu Ọmọ Ọlọrun, ẹ jẹ ki a di ijẹwọ wa mu ṣinṣin.

    Àkíyèsí: Jesu duró gẹ́gẹ́ bi ètùtù fún ẹ̀ṣẹ̀ wa ati olórí alufa wa ní ọrun, ti o ṣe ohun ohun ìyanu meji fún wa. Ohun àkọ́kọ́ ni ìyípaọ̀ dà ìgbé-ayé pátápátá ti a npè ni ìbí titun, pẹlu ìdáríhì gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ atẹhinwa (Johannu 3:3-6; Romu 3:25). Ekeji ni agbára lati ma a gbé ìgbé-ayé rere nisisinyi ati ni ọjọ́ iwájú (Titu 2:14; Fillipi 2:13). Awọn ohun meji yi lo nsọ ènìyàn di olododo, èyí ti o túmọ̀ sí pé ibaṣepọ̀ to dára wà laarin ẹni náà ati Ọlọrun. Kò si ọ̀nà ti ẹnikan le gba di olododo pẹlu àwọn iṣẹ́ (akitiyan ara rẹ̀), nitori ododo ma nwá lati inu oore-ọ̀fẹ́ ti Jesu ma nfi funni (Iṣe Awọn Aposteli 4:12). Èyi ni ododo nípa ìgbàgbọ́, eyi ti iṣe ododo otitọ́ kan soso.

12. Kinni awọn ìlérí ìyanu mẹ́fà ti Bibeli fi fún wa nípa ododo tí Jesu fi lélẹ̀ fun wa?
    A. Yio bo gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ wa atijọ́ ati pé yio tún ka wá gẹ́gẹ́ bi alailẹbi (Isaiah 44:22, 1 Johannu 1:9).
    B. Jesu ṣe ìlérí lati dáwa padà sí àwòrán Ọlọrun (Romu 8:29).
    D. Jesu nfún wa ni ìfẹ́ ati agbára lati má a se ìfẹ́ Ọlọrun (Fillipi 2:13)
    E. Jesu yio ràn wa lọ́wọ́ lati ṣe awọn ohun to tẹ́ Ọlọrun lọ́rùn (Heọ́ beru 13:20,21; 1 Johannu 3:22)
    Ẹ. O pa ìwé akọsilẹ̀ ikú wa rẹ́ nipa fífún wa ni idalare fun igbé-ayé àìlẹ́ṣẹ̀ Rẹ̀ àti ẹ̀jẹ̀ ti o fi sètùtù ikú (2 Korinti 5:21).
    F. Jesu gba ojuse ati ràn wá lọ́wọ́ ní pípa wa mọ́ ni ododo titi yi O fi padà wá (Fillipi 1:6; Juda 24).

    Àkíyèsí: Jesu ti ṣetán lati mu gbogbo ileri ologo wọ̀nyí ṣẹ ninu ayé rẹ. Njẹ́ o ṣetán? Kunlẹ bayi ki o si wipé ki Jesu gba àkoso ayé rẹ. Ko ni ja ọ kulẹ̀.

13. Njẹ́ ẹnikan nílò lati ko ipa kankan lati di olododo?
    **Matteu 7:21**
    Ki iṣe gbogbo ẹniti npè mi li Oluwa, Oluwa, ni yio wọle ijọba ọrun; bikose ẹniti _________ _________ ti Baba mi ti mbẹ li ọrun.

    Àkíyèsí: Bẹ́ẹ̀ni, ojuse ti wa ni lati yi ọkàn àti ìfẹ́ wa padà si ọ̀dọ̀ Jesu, ki a si fi ààyè gbà A lati ma a sàkóso. A gbọ́dọ̀ gbà á gbọ pẹlu sise akoso gbogbo ayé wa. Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ lo gbàgbọ́ pe, Jesu yio mu gbogbo àwọn to npe orukọ Rẹ̀ lọ sí ọrun, laiwo bí wọn ṣe nhùwà. Ṣùgbọ́n òkú ìgbàgbọ́ yi ki iṣe otitọ́ (Matteu 7:14).

14. Kilo ṣẹlẹ̀ ni ọjọ́ ètùtù?
    **Lefitiku 16:30**
    Nitori pe li ọjọ́ naa li a o ṣètùtù fun nyin, lati _________ nyin mọ́; ki ẹnyin ki o le mọ́ kúrò ninu gbogbo _________ nyin niwaju OLUWA.

    Àkíyèsí: Ọjọ́ ètùtù jẹ́ ọjọ́ idakẹjẹ ti idajọ́ t'ó ma nwáyé ni Israeli ni ẹkan ní ọdún (Lefitiku 23:27). Gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ ni a gbọ́dọ̀ jẹ́wọ́ ki a si kọ̀ wọn sílẹ̀. Ẹniti o ba kọ, oun li a o ké kúrò ninu awọn eniyàn rẹ̀ títí láí ni ọjọ́ náà (ẹsẹ ẹ̀ó). Ni ọjọ́ naa, ewúrẹ́ meji li a yàn. Ọ̀kan fun Oluwa ati ekeji fun ewúrẹ́ idasilẹlọ, ti o dúró fun eṣu (Lefitiku 16:7,8). Ewúrẹ́ ti Oluwa li a pa lati fi rúbọ ẹ̀ṣẹ̀ fun awọn eniyàn (ẹsẹ 9). Ẹ̀jẹ̀ rẹ ni a gbé wọ ibi mímọ́ julọ lati fi wọ́n iwájú ati orí ìtẹ́-àànú (ẹsẹ 14). Ni ọjọ́ idajọ́ yi nìkan ni olórí alufa ma nwọ inú ibi mímọ́ jùlọ. Ẹ̀jẹ̀ ti a wọ́n (dúró fun ìrubọ Jesu) ní Ọlọrun tẹ́wọ́gbà, gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ tí àwọn eniyàn jẹ́wọ́ li o lọ kúrò lara ibi mímọ́ si ara olori alufa. Lẹhin naa ni olori alufa jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ naa padà sí ara ewúrẹ́ idasilẹlọ, a sì rán ewúrẹ́ náà lọ si inú ijù, a sì gbàgbé rẹ (ẹsẹ ẹ̀ù,ẹ̀ò,ẹ̀ẹ̀). Ní ọ̀nà yí, àgọ́ naa yio di wíwẹ̀mọ́ kurò ninu ẹ̀ṣẹ̀ awọn ènìyàn ti o ti wà ni ara rẹ̀, nigbàti a wọ́n ẹ̀jẹ̀ yíká rẹ̀ ní gbogbo ọdun to ti kọjá.

15. Njẹ́ ọjọ́ ètùtù li atijọ́ se ìkìlọ̀ iwẹnumọ́ ibi mímọ́ ti ọrun ?
    **Heberu 9:23**
    Nitori naa a kò le ṣai fi iwọnyi wẹ̀ awọn apẹrẹ ohun ti mbẹ lọrun mọ́; ṣùgbọ́n o yẹ ki a fi ẹbọ ti o _________ ju iwọnyi lọ wẹ̀ awọn ohun _________ paapaa mọ.

    Àkíyèsí: Bẹ́ẹ̀ni! Ìjọsìn ọjọ́ naa ntọ́ka sí bí Jesu ti pa ẹ̀ṣẹ̀ rẹ́, olori alufa wa ní ibi mímọ́ tọ̀run. Jesu wa ni ọrun lati ṣe ìlàjà fun awọn ènìyàn Rẹ̀ ati pé Ó dúró lati mú ẹ̀ṣẹ̀ awọn ti o ba gbàgbọ́ ninu ẹ̀jẹ̀ Rẹ̀ tó ta silẹ̀ kúrò. Ètùtù ní atijọ́ bí i ti Yom Kippur ti Israeli, ntọka sí ètùtù tó gbẹ̀hìn tí a o ṣe fun ayé. Ètùtù tó gbẹ̀hìn yí ni yio yọrí sí ìdájọ́ to kẹ̀hìn, ti yio yanjú ibéèrè nípa ẹ̀ṣẹ̀ ti o wa ninu ayé gbogbo ènìyàn títí lai. Ẹkọ́ wa ti o nbọ̀ fihàn bi Ọlọrun ṣe mu ọjọ́ fun ìgbà ti ìdájọ́ ti ọrun yio bẹ̀rẹ̀. Ayọ̀!

# Èsì Rẹ

Ṣe o fẹ́ lati gbé ayé rẹ le Jesu lọ́wọ́ pátápátá, ki Jesu le ṣe iṣẹ iyanu ti o tọ́ lati mu o di olododo ní ayé rẹ?

ÌDÁHÙN:_____________________





©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP15.indd 2 12/7/12 10:58 AM